## Àwọn Àṣẹ Ilé-ẹjọ́

Àwọn Àṣẹ Abélé ni Àwọn ilé-ẹjọ́ tó ń rí sí ọ̀rọ̀ Ẹbí lè fún ọ fún ààbò rẹ. Àwọn ènìyàn tí wọ́n lè bèrè fún àwọn àṣẹ ni:

- Àwọn tọkọ-taya tàbí àwọn tọkọ-taya tẹ́lẹ̀ rí
- Àwọn alábàáṣepọ̀ tàbí àwọn alábàáṣepọ̀ tẹ́lẹ̀ rí
- Àwọn ènìyàn tí wọ́n ní ọmọ papọ̀
- Àwọn ènìyàn tí wọ́n ti ń fẹ́ ara wọn sọ́nà
- Tí o bá ní ọmọ tí ó ti dàgbà tí ó ń hùwà ipá
- Àwọn mọ̀lẹ́bí méjì tí ó ń gbé papọ̀ ní ìbáṣepọ̀ tí kò ní àdéhùn

Àṣẹ Abélé ń dènà onílòkulò láti:

1.Lò tàbí dẹ́rùbá ni láti lo ìwà-ipa sí tàbí láti máa hùwà ní ọ̀nà tí ó fi alùgbàdì tàbí àwọn tí wọ́n wà ní abẹ́ wọn sínú ìbẹ̀rù.

2. Wíwò tàbí wíwá sí ilé alùgbàdì tàbí ẹni tí ó wà ní abẹ́ wọn.

3. Títẹ̀lé tàbí níní ìbásọ̀rọ̀ (tí ó fi mọ́ ìbánisọ̀rọ̀ orí ẹ̀rọ) pẹ̀lú alùgbàdì tàbí ẹni tí ó wà ní abẹ́ wọn.

## Irú àwọn Àṣẹ Ilé-ẹjọ́

***Àṣẹ Ìdáàbòbò***

Ó wà títí ìpinnu Ilé-ẹjọ́ lórí Àṣẹ Ààbò/Ìdènà.

***Àṣẹ Ààbò***

Ó wà títí ọdún 5.

***Àṣẹ Ìdádúró***

Ó wà títí ọdún 3 - Àwọn Àṣẹ Ìdènà ní àfikún àwọn májẹ̀mú pé onílòkulò gbọdọ̀ kúrò nínú ilé náà tí wọ́n bá ń gbé pẹ̀lú alùgbàdì wọn a kò sí fàyè gbà á láti wọ inú ilé títí tí àṣẹ náà máa fi parí.

Fún àmọ̀ràn sì lóri àwọn Àṣẹ Ilé-ẹjọ́





## Kàn sí Ibùdó ti Abẹ́lẹ́ Garda rẹ

**Láti wá ibùdó rẹ ti Garda abẹ́lé ọ̀wọ́ ṣàyẹ̀wò**

## Àwọn Iṣẹ́ Àtìlẹ́yìn Mìíràn

**Tí o bá ń kojú èyíkéyìí àwọn ìhùwàsí wọ̀nyìí tàbí ò ń kọminú nípa ẹlòmíràn**

Jọ̀wọ́ ṣàyẹ̀wò fún àwọn iṣẹ́ àtìlẹ́yìn obìnrin nípasẹ̀ agbègbè

**Women's Aid**
**1800 341 900**
Ìlà-ìrànlọ́wọ́ Fóònù ọ̀fẹ́ Orílẹ̀-èdè wà ní àwọn èdè tí ó lé ní 200 ní 24/7

**Men's Development Network**
**1800 816 588**
**Ajé & Ọjọ́rú:** 10am-6pm;
**Ọjọ́-ìṣẹ́gun & Ọjọ̀bọ̀:** 12-8pm;
**Ẹtì, Àbámẹ́ta, Àìkú, Ìsinmi Ilé-ìfowópamọ́:** 2-6pm

**Ojúkò Rògbòdìyàn Ìfipábánilòpọ̀**
**1800 77 88 88**
Ìlà-ìrànlọ́wọ́ Rògbòdìyàn Ìfipábánilòpọ̀ wà ní àwọn èdè tí ó jú 200 24/7

**Childline**
**1800 66 66 66**
Ìlà-ìrànlọ́wọ́ àwọn Ọmọdé Orílẹ̀-èdè ní 24/7

**Men's Aid**
**(01) 554 3811**
Ìlà-ìrànlọ́wọ́ Aláṣìírí Orílẹ̀-èdè
Ọjọ́-ajẹ́ - Ọjọ́-ẹtì 9am -5pm

**Safe Ireland**
**www.safeireland.ie**

**www.whatwouldyoudo.ie**



# ÌLÒKULÒ ABẸ́LÉ
AN GARDA SÍOCHÁNA

O kò dánìkan wà.
A wà níbí láti tẹ́tí sí ọ.
A wà níbí láti ràn ọ́ lọ́wọ́

Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí ìlòkulò abẹ́lé ṣe àbẹ̀wò sí garda.ie tàbí kí o ṣàyẹ̀wò kóòdù QR ìsàlẹ̀ yìí

Tì o bá nílò ìrànlọ́wọ́ tàbí o wà nínú ewu lójú ẹsẹ̀ tàbí o nílò Gardai, pe 999 tàbí 112.

## Kínni Ìlòkulò Abélé?

Ṣíṣe àtìléyìn fún àti dídáàbò bo àwọn alùgbàdì ìṣèlẹ̀ ìlòkulò abélé ṣe pàtàki jùlọ fún Garda Síochana.

Ìloòkulò abélé lè gba oríṣìí ọ̀nà wáyé; ó lè jẹ́ ajẹmọ́ àfojúrí, ìbánilòpọ̀, ìmọ̀lára, ọpọlọ, ìnáwó tabí ìlòkulò lórí ayélujára/ onídíjítà.

Ó lè ṣelẹ̀ nínú ẹbí láàrin mọ̀lẹ́bí kan sí òmíràn. Ó lè níí ṣe pẹ̀lú alábàáṣepọ̀ lọ́wọ̀lọ́wọ́ tàbí ti tẹ̀lẹ́, láì ka ẹ̀yà ọkùnrin tàbí obìnrin sí tàbí àgbóyé ìbálòpọ̀. Ó lè níí ṣe pẹ̀lú àwọn méjì tí wọ́n jọ ń fẹ́ra wọn tí wọ́n kò tíì tó ọmọ ọdún 18.

Ọ̀kan nínú àwọn obìnrin mẹ́rìn-in àti ọ̀kan nínú àwọn ọkùnrin méje ní wọ́n jẹ́ alùgbàdì ìṣèlẹ̀ ìlòkulò abélé.

## Ǹjé ominú ń kan ọ́ nípa ìbátan/ọ̀rẹ́ tàbí akẹgbẹ́ rẹ bí?

| | |
|---|---|
| TẸ́TÍ | GBÀGBỌ́ |
| FI ÌDÁNILÓJÚ HÀN | ṢE ÀTÌLẸ́YÌN |

*Ní kété tí ẹnìkan bá ti fi àṣírí sí ọ lọ́wọ́ nípa ìlòkulò abélé, má ṣe fi ìmọ̀lára tí ó ń funni-lára hàn sí onílòkulò náà, èyí lè fi alùgbàdì sínú ewu tí ó ju ti tẹ̀lẹ̀ lọ*



## Ǹjẹ́ o wà nínú ìbáṣepọ̀ ìlòkulò bí?

- Ǹjẹ́ ò ń bẹ̀rù alábàáṣepọ̀ rẹ bí? Ṣe alábàáṣepọ̀ rẹ ń dẹ́rù bà ọ́?
- Ṣé alábàáṣepọ̀ rẹ máa ń tètè bínú, lo ipá tàbí lérí láti lo ipá lòdì sí ọ tàbí àwọn ọmọ rẹ?
- Ǹjẹ́ alábàáṣepọ̀ rẹ máa ń lérí láti pa ọ́ tí o bá lọ?
- Ǹjẹ́ alábáṣepọ̀ rẹ kẹ́gàn, bàọ́jẹ́, dójútì tàbí bú ọ?
- Ṣé o rò pé o wà ní ìyàsọ́tọ̀ kúrò lọ́dọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ àti ẹbí rẹ? Ǹjẹ́ alábàáṣepọ̀ rẹ máa ń jowú àwọn ọ̀rẹ́ rẹ tàbí tí o bá ń bá àwọn ènìyàn mìíràn sọ̀rọ̀?
- Ṣé alábàáṣepọ̀ rẹ ló ń ṣàkóso àwọn ìgbòkègbodò rẹ ojoojúmọ́, ìnáwó tàbí àwọn ọ̀rọ̀-ìgbaniwọlé, àwọn ímeèlì/àwọn àkántì ayélujára rẹ?
- Ǹjẹ́ alábàáṣepọ̀ rẹ máa ń fi ipá mú ọ ní ìbálòpọ̀ nígbà tí o kò fẹ́ láti ṣe é?
- Ǹjẹ́ alábáṣepọ̀ rẹ máa n béèrè fún irú ìbáńílòpọ̀ tí kò bá ọ lára mu?



## Àwọn àfihàn afikún ewu

- Ìhùwwàsí Ìfipámúni àti fífi ẹ̀rù ṣàkóso ẹni
- Titele
- Ìṣàkọlù - ní ojúkojú tàbí nígbà ìbálòpọ̀
- Ìfúnnilọ́rùn tàbí dídí èémí lọ́wọ́
- Lílo ohun ìjà
- Ìfìyàjẹni lásìkò oyún
- Pípa Nǹkan ọ̀sìn tàbí ẹranko
- Ìhàlẹ̀ láti gbẹ̀mí ara-ẹni tàbí ìhàlẹ̀ láti pa alábàáṣepọ̀ tàbí àwọn ọmọ ẹni
- Alùgbàdì fi tàbí ó ń múra láti fi ìbáṣepọ̀ náà sílẹ̀

Tì o bá nílò ìrànlọ́wọ́ tàbí o wà nínú ewu lójú ẹsẹ̀ tàbí o nílò Gardai, pe 999 tàbí 112.

## Àwọn iṣẹ́ Àtìlẹ́yìn

Tí o bá ń kojú èyíkéyìí àwọn ìhùwàsí wọ̀nyìí tàbí ò ń kọminú nípa ẹlòmíràn, àwọn iṣẹ́ àtìlẹ́yìn ìfìyàjẹni abélé wà jákèjádò orílẹ̀-èdè yìí fún àwọn ọkùnrin àti àwọn obìnrin tí wọ́n lè ṣe ìrànwọ́ pẹ̀lú àmọ̀ràn lórí ìṣètò ààbò, pèsè àtìlẹ́yìn fún àwọn alùgbàdì tí wọ́n sì tún lè ṣe ìrànwọ́ pẹ̀lú bíbéèrè fún àwọn àṣẹ ilé-ẹjọ́.

Tí o bá jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin tí ó ń kojú ìfìyàjẹni abélé tàbí ìfìyàjẹni ajẹmọ́ ìbálòpọ̀ ààpù kan wà tí à ń pè ní Ààpù Bright Sky tí ó ń pèsè àlàyé lórí ìfìyàjẹni abélé àti àwọn iṣẹ́ àtìlẹ́yìn tí ó wà ní orílẹ̀-èdè.